# Ojú-ewé Ọ̀rọ̀ Àfikún-àkókò Fún Àwọn Olùpèsè Kọ̀ọ̀kan

Ojú-ewé ọ̀rọ̀ yìí ni a ṣe láti ṣèrànwọ́ fún Àwọn Olùpèsè Kọ̀ọ̀kan láti lóye àwọn òfin nípa àwọn òdíwọ̀n ọ̀sẹ̀ iṣẹ́ àti àfikún-àkókò. Jọ̀wọ́ kàn sí aṣàkóso ẹjọ́ oníbàárà tàbí ṣàbẹ̀wò www.dshs.wa.gov/altsa/IPOT fún àlàyé síwájú síi.

## ÀLÀYÉ ÀFIKÚN-ÀKÓKÒ GBOGBOGBÒ

### 1. Kínni 'ọ̀sẹ̀ iṣẹ́'?

Ọ̀sẹ̀ iṣẹ́ bẹ̀rẹ̀ ní ọjọ́ Àìkú ní aago 12:00 òwúrọ̀ (òòru) ó sì parí ní ọjọ́ Àbámẹ́ta tó tẹ̀lée ní aago 11:59 ọ̀sán.

### 2. Kínni Òdíwọ̀n Ọ̀sẹ̀ Iṣẹ́ (WWL)?

WWL jẹ́ àpapọ̀ iye àkókò iṣẹ́ tí o ṣe láàrín ọ̀sẹ̀ iṣẹ́ kan. Òfin ilẹ̀ Washington 2016 ṣètò òdíwọ̀n lórí iye wákàtí tí Olùpèsè Kọ̀ọ̀kan (IP) le fi ṣiṣẹ́ láàrín ọ̀sẹ̀ iṣẹ́ kan. Gbogbo IP ló ní òdíwọ̀n ọ̀sẹ́ iṣẹ́ (WWL). O le ṣiṣẹ́ tó WWL rẹ nígbàtí a bá ti yan àwọn wákàtí náà fún ọ nípasẹ̀ ọ̀kan tàbí ọ̀pọ̀ àwọn oníbàárà àti pé oníbàárà tí o ṣiṣẹ́ fún lẹ́tọ̀ọ́ láti gba wákàtí náà. Oníbàárà le má yàn ju iye wákàtí oṣoṣù tí a yẹ̀wò lọ nínú Ètò Ìtọ́jú wọn. Àwọn WWL ń ṣèrànwọ́ láti darí iye owó àfikún-àkókò láti ṣarídájú pé owó iṣẹ́ wà nílẹ̀ fún gbogbo àwọn tí nílò wọn.

### 3. Báwo ni DSHS ṣe ń pinnu WWL ìgbà pípẹ́ mi àti pé báwo ni mo ti le mọ WWL ìgbà pípẹ́ mi?

A ṣòfin ìpínlẹ̀ kan ní Oṣù Kẹ̀ẹrin Ọdún 2016. Òfin yìí fi ìdí wákàtí 40 WWL múlẹ̀ fún gbogbo IP àyàfi fún àwọn tó ṣiṣẹ́ fún àpọ̀jù wákàtí iṣẹ́ 40 láàrín ọ̀sẹ̀ ní Oṣù Kínní Ọdún 2016. Àwọn WWL tó ju wákàtí 40 lọ ni a pinnu nípa pínpín àwọn wákàtí iṣẹ́ Oṣù Kínni Ọdún 2016 tí a ti san nípa 4.33 tí a sì ṣàkótán rẹ̀ sí ìdá mẹ́rin wákàtí. Ní Oṣù Kaàrún Ọdún 2016, DSHS fi àwọn àkíyèsí kan ránṣẹ́ sí IP tó ṣiṣẹ́ ní Oṣù Kínní Ọdún 2016 pẹ̀lú àlàyé WWL wọn. Kò sí WWL ìgbà pípẹ́ tó le kọjá wákàtí 65. Tí o bá iṣẹ́ bíi IP lẹ́yìn Oṣù Kínní Ọdún 2016, WWL rẹ jẹ́ wákàtí 40.

### 4. Tí mo bá rò pé a pinnu WWL ìgbà pípẹ́ mi ní àìtọ̀nà ńkọ́?

Tí o bá rò wípé a pinnu WWL rẹ ní àìtọ̀nà, o le fi ìbèrè kan ránṣẹ́ sí aṣàkóso ẹjọ́ oníbàárà àti pé DSHS yóò tún ṣàyẹ̀wò àwọn wákàtí rẹ nípasẹ̀ Kóòdù Àbòjútó ti Washington 388-114-0050.

### 5. Ṣé WWL ìgbà pípẹ́ mi le yípadà láíláí bí?

Tí WWL ìgbà pípẹ́ rẹ bá wà láàrín wákàtí 60.25 àti 65, yóò wálẹ̀ sí wákàtí 60 ní Ọjọ́ 1 Oṣù Keèje, Ọdún 2017 àyàfi tí àyípadà bá wà sí òfin náà. Bí bẹ̀ẹ̀kọ́, WWL ìgbà pípẹ́ rẹ kò ní yípadà fún ìwọ̀n ìgbà tí o sì yẹ bíi IP kan. WWL rẹ yóò tún wà bákanáà tí o bá sínmi lẹ́nu iṣẹ́ fún ìgbà díẹ̀ tí o sì padà bíi IP kan ní ọjọ́ iwájú.

### 6. Irú àwọn iṣẹ́ wo ní ó wà nínú wákàtí iṣẹ́ nínú WWL mi?

- Ìtọ́jú Ara Ẹni
- Ìtọ́jú Ìgbà Ìsinmi
- Ìkẹ́kọ̀ọ́ Níní Ìmọ̀
- Ìtọ́jú Àìlera

### 7. Ṣé a le ṣàmúlò WWL mi sí àkókò ìrìn-àjò, ìkẹ́kọ̀ọ́ tí DSHS nílò, tàbí ìsanwó àkókò ìsinmi (PTO)?

Bẹ́ẹ̀kọ́. Àkókò ìrìn-àjò, ìkẹ́kọ̀ọ́ tí DSHS nílò àti PTO ni kò sí nínú WWL rẹ. Èyí túmọ̀ sí wípé o le ṣiṣẹ́ títí àwọn iṣẹ́ ṣíṣe WWL rẹ fún oníbàárà bá ti nílò, kódà láàrín ọ̀sẹ̀ tí o ti nílò ìkẹ́kọ̀ọ́, àkókò ìrìn-àjò tí a fọwọ́sí, tàbí gba PTO.

ÌSANWÓ ÀFIKÚN-ÀKÓKÒ (OT)

**8. Báwo ni a ti ń ṣírò OT mi tí a san?**

A ń sanwó iṣẹ́ tí o ṣe fún ọ fún gbogbo àkókò tí o fi ṣiṣẹ́ èyí tí ó tó wákàtí 40 nínú ọ̀sẹ̀ iṣẹ́ kan. Fún gbogbo àkókò tí o fi ṣiṣẹ́ tí ó ju wákàtí 40 lọ, a ń sanwó fún ọ ní iye ìgbà 1.5 iye owó tí ó yẹ kí o gbà. Ìlànà ìsanwó IPOne ń san ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ owó àwọn wákàtí tí o fi ṣiṣẹ́ nínú ọ̀sẹ̀ iṣẹ́ kan ni déédé iye owó tí o ń gbà (tí a tọ́ka sí bíi "ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ iye owó"). Ń ṣàfihàn OT bíi àfikún ìpin 1/2 fún wákàtí OT. Àwọn àpapọ̀ náà ni a ròpọ̀ fún ìsanwó lápapọ̀.

*Àpẹrẹ:*

*O ṣiṣẹ́ fún wákàtí 45 nínú ọ̀sẹ̀ iṣẹ́ kan àti pé iye owó rẹ jẹ́ $12 fún wákàtí kan.*
*Iye owó rẹ yóò jẹ́:*
*Wákàtí 45 x $12 wákàtí kan (ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ iye owó) = $540*
*+ Wákàtí 5 ti àfikún-àkókò x $6 (ìlàjì owó) = $30*
*Àpapọ̀ $540 +$30 = $570*

OT ń farahàn nínú Àpèjúwe Ìsọníṣókí Ìsanwó tí a sì pín sí wẹ́wẹ́ nínú Abala Àpawọlé. Nínú àpẹrẹ yìí Abala Àpawọlé yóò ṣàfihàn wákàtí 45 ìtọ́jú ara ẹni àti wákàtí OT 5.

**9. Ṣé a ó sanwó fún mi fún àkókò ìrìn-àjò, ìkẹ́kọ̀ọ́ tí DSHS nílò, tàbí ìsanwó àkókò ìsinmi (PTO)?**

A ó sanwó OT fún ọ fún àkókò ìrìn-àjò àti ìkẹ́kọ̀ọ́ tí DSHS nílò tí àpapọ̀ wákàtí tí o fi ṣiṣẹ́ ní ọ̀sẹ̀ iṣẹ́ bá ju 40 lọ. Àwọn wákàtí PTO ni a kò kàn kún wákàtí tí o fi ṣiṣẹ́, fún ìdí èyí wọn kò yẹ fún ìsanwó OT.

ÀLÀYÉ FÚN ÀWỌN IP TÍ WỌ́N NÍ WWL WÁKÀTÍ 40 ÌGBÀ PÍPẸ́

**10. Ṣé mo le ṣiṣẹ́ ju wákàtí 40 lọ láàrín ọ̀sẹ̀ iṣẹ́ kan?**

O le má ṣiṣẹ́ ju wákàtí iṣẹ́ 40 lọ nínú ọ̀sẹ̀ iṣẹ́ kan àyàfi tí o bá ti gba ìfọwọ́sí pàtó ti oníbàárà láti DSHS láti ṣiṣẹ́ fún ìgbà díẹ̀ ju wákàtí 40 lọ.

**11. Ṣé mo le ṣiṣẹ́ ju WWL ìgbà pípẹ́ mi lọ tí mo bá ṣiṣẹ́ fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ oníbàárà?**

O gbọ́dọ̀ ṣàkóso gbogbo wákàtí iṣẹ́ oníbàárà láàrín WWL ìgbà pípẹ́ rẹ, èyí tó wù kí iye oníbàárà tí o ṣiṣẹ́ fún jẹ́. Tí o bá ṣiṣẹ́ fún ju oníbàárà kan lọ, o gbọ́dọ̀ ṣètò àkókò rẹ pẹ̀lú ìkọ̀kan wọn láti ṣarídájú pé, nígbàtí o bá ṣàfikún àwọn wákàtí iṣẹ́ rẹ papọ̀, o kò ṣiṣẹ́ ju WWL ìgbà pípẹ́ rẹ lọ.

**12. Kínni kí ń ṣe tí oníbàárà tí mo ṣiṣẹ́ fún bá fẹ́ ṣètò mi láti ṣiṣẹ́ fún ọ̀pọ̀ wákàtí ju ohun tí mo ní lọ nínú WWL ìgbà pípẹ́ mi?**

- Ṣàlàyé pé a kò gbà ọ́ láàyè láti ṣiṣẹ́ ju WWL rẹ lọ àti pé ṣíṣe bẹ́ẹ̀ ni a ó rí bíi àpọ̀jù ìbéèrè. Wò fún àfikún àlàyé lórí àpọ̀jù ìbéèrè.
- Máṣe gba iṣẹ́ tí yóò jẹ́ kí o ṣiṣẹ́ kọjá WWL rẹ lọ.
- Gba oníbàárà nímọ̀ràn láti lo olùpèsè míràn.
- Gba oníbàárà nímọ̀ràn láti kàn sí aṣàkóso ẹjọ́ rẹ̀ tí oníbàárà bá kọ̀ jálẹ̀ láti lóye òdiwọ̀n rẹ tàbí kò le rí olùpèsè míràn.
- Jọ̀wọ́ wo #18 lórí ojú-ewé 3 fún àfikún àlàyé lórí àwọn ìní tó jẹyọ àti pàjáwìrì.

**ÀLÀYÉ FÚN ÀWỌN IP TÓ NÍ WWL ÌGBÀ PÍPẸ́ TI WÁKÀTÍ 40.25 TÀBÍ JÙ BẸ́Ẹ̀ LỌ**

**13. Ṣé mo le ṣiṣẹ́ ju wákàtí 40 lọ nínú ọ̀sẹ̀ iṣẹ́ kan?**

Tí o bá gba àkíyèsí àkọsílẹ̀ láti DSHS pé WWL ìgbà pípẹ́ rẹ ju 40 lọ tàbí tí o a bá ní àfikún WWL pàtó oníbààrà ìgbà díẹ̀ tí a fọwọ́sí, o le ṣiṣẹ́ dé iye wákàtí tí a sọ nínú àkíyèsí rẹ.

**14. Kínni kí ń ṣe tí mo bá ṣiṣẹ́ fún ju oníbààrà kan lọ?**

Jọ̀wọ́ wo ìdáhùn sí ìbéèrè #11.

**15. Tí oníbààrà tí mo ń ṣiṣẹ́ fún bá fẹ́ kí n ṣàtúnṣe wákàtí mi láti ṣiṣẹ́ púpọ̀ ju WWL ìgbà pípẹ́ mi lọ nínú ọ̀sẹ̀ iṣẹ́ kan?**

le ṣàtúnṣe àwọn wákàtí rẹ tí gbogbo ìwọ̀nyí bá jẹ́ ònítọ́:

- Oníbààrà náà ní àìní; àti
- Ṣíṣe iṣẹ́ àfikún wákàtí kò ní kọjá àwọn wákàtí tí oníbààrà yẹ̀wò ní oṣoṣù; àti
- Ṣíṣe iṣẹ́ púpọ̀ ní ààrín ọ̀sẹ̀ kan kò ní yọrísí kí oníbààrà máa lọ láìsí ìtọ́jú pàtàkì ní àwọn ọ̀sẹ̀ míràn láàrín oṣù; àti
- Ṣíṣe iṣẹ́ púpọ̀ ní ààrín ọ̀sẹ̀ kan kò ní ṣokùnfà fún ọ láti ṣiṣẹ́ àfikún-àkókò púpọ̀ nínú oṣù ju bí o ti máa ṣe bí o bá ṣiṣẹ́ dé ibi WWL rẹ ní gbogbo ọ̀sẹ̀ ti oṣù náà.

Nígbàtí WWL rẹ bá ju 40 lọ, o le ṣàtúnsẹ wákàtí rẹ bí o ti fẹ́ tó bá ti jẹ́ wípé o kò ní ṣe àfikún-àkókò púpọ̀ nínú oṣù ju bí o ti máa ń ṣe lọ. Iye owó wákàtí àfikún-àkókò oṣoṣù ni a ń ṣírò nípa yíyọ wákàtí 40 kúrò nínú WWL rẹ kí a si sọ èyí tó kù di púpọ̀ nípa iye Ọjọ Àbámẹ́ta nínú oṣù náà.

<u>*Àpẹrẹ:*</u>

*WWL ti Jose jẹ́ wákàtí 46. Iye àfikún-àkókò oṣoṣù tí Jose le fi ṣiṣẹ́ dá lórí iye Ọjọ́ Àbámẹ́ta nínú oṣù tó fi ń ṣiṣẹ́.*

***Ìṣirò Ọjọ́ Àbámẹ́ta 5:*** *46 – 40 = 6 x 5 = 30*

***Ìṣirò Ọjọ́ Àbámẹ́ta 4:*** *46-40=6 x 4 = 24*

*Oníbààrà ti Jose bá ṣiṣẹ́ fẹ́ kó ṣiṣẹ́ ní ìrọ̀rùn ní gbogbo oṣù náà, èyítí Jose le ṣe tí kò bá ti ṣiṣẹ́ ju wákàtí 30 fún àfikún-àkókò nínú àwọn oṣù tó ní Ọjọ́ Àbámẹ́ta 5, tàbí wákàtí 24 ti àfikún-àkókò nínú àwọn oṣù tó ní Ọjọ́ Àbámẹ́ta 4.*

O tún le ṣàtúnṣe àwọn wákàtí rẹ láti ṣiṣẹ́ ju WWL rẹ lọ tí oníbààrà tí o ń ṣiṣẹ́ fún bá ra àwọn wákàtí àfikún-àkókò púpọ̀ àwọn ètò-ìṣúná New Freedom tàbí Veteran Directed Homecare Services.

**16. Kínni kí ń ṣe tí oníbààrà tí mo ṣiṣẹ́ fún bá fẹ́ ṣètò mi láti ṣiṣẹ́ fún ọ̀pọ̀ wákàtí àfikún-àkókò oṣoṣù àpapọ̀ ju ohun tí mo ní lọ nínú WWL ìgbà pípẹ́ mi lọ?**

Jọ̀wọ́ wo ìdáhùn sí ìbéèrè náà #12.

**ÒDIWỌ̀N Ọ̀SẸ̀ IṢẸ́ PÀTÓ ONÍBÀÁRÀ ÌGBÀ DÍẸ̀ (CSWWL)**

**17. Kínni CSWWL onígbà díẹ̀?**

Oníbààrà tí o ń ṣiṣẹ́ fún le bèrè DSHS láti ṣàfikún WWL rẹ fún ìgbà díẹ̀ nígbàtí ń wá àwọn olùpèsè míràn láti bá àìní wọn pàdé. DSHS yóò dá ọ lóhùn nípasẹ̀ méèlì pẹ̀lú ìfọwọ́sí tàbí sísẹ́ ìfọwọ́kọ. Tí a bá fọwọ́síí, àkíyèsí náà yóò tún sọ fún ọ déètì tí ìfọwọ́sí náà bẹ̀rẹ̀ àti tí ó parí àti iye àkókò tí a fọwọ́sí. Oníbààrà tí o ṣiṣẹ́ fún yóò sì gba ẹ̀dà kan pẹ̀lú. Ìwífúnni tí a kọ tàbí bèrè yìí ni a tún mọ̀ sí ìbèrè CSWWWL. DSHS kò ní fọwọ́sí WWL onígbà díẹ̀ tó kọjá wákàtí oṣoṣù tí oníbààrà ń yẹ̀wò.

ÀWỌN ÀÌNÍ PÀJÁWÌRÌ

18. **Kínni kí n ṣe tí mo bá ti ṣiṣẹ́ gbogbo wákàtí nínú WWL mi ṣùgbọ́n oníbàárà náà ní àìní pàjáwìrì tó sì jẹ́ lójú ẹsẹ̀ mo sì gbọ́dọ̀ máa tẹ̀síwájú láti ṣiṣẹ́ láti ṣàtìlẹ́yìn fún ìlera àti ààbò oníbàárà náà?**
    - Dúró pẹ̀lú oníbàárà títí ohun gbogbo yóò fi wà lábẹ́ ààbò tó sì ti yanjú.
    - Tí pàjáwìrì bá wà tó nílò àwọn iṣẹ́ ìlera pàjáwìrì, pe 9-1-1.
    - Parí iṣẹ́ òjọ́ rẹ kété tí ohun gbogbo bá ti yanjú.
    - Kàn sí aṣàkóso ẹjọ́ náà ní ọjọ́ kejì láti ṣàlàyé ohun tó ṣẹlẹ̀.

ÌBÈRÈ ÀPỌ̀JÙ

19. **Kínni ìbèrè àpọ̀jù?**
    Ìbèrè àpọ̀jù ń wáyé nígbàtí:
    - ṣe ọ̀pọ̀ wákàtí iṣẹ́ ní oṣù kan ju ohun tí a gbà ọ́ láàyè láti ṣe lọ; tàbí
    - ṣe ọ̀pọ̀ wákàtí iṣẹ́ ju WWL rẹ lọ tí a kò fọwọ́sí nípasẹ̀ DSHS; tàbí
    - bèrè ọ̀pọ̀ àkókò ìrìn-àjò ju ohun tí a gbà ọ́ láàyè láti pèsè nínú ọ̀sẹ̀ iṣẹ́ kan lọ.

20. **Kínni Ìṣe Àdéhùn?**

Ìṣe àdéhùn jẹ́ àkíyèsí kan tí a firánṣẹ́ sí ọ nípasẹ̀ DSHS. Àkíyèsí náà ń sọ fún ọ pé o ti ṣe ọ̀pọ̀ wákàtí iṣẹ́ tàbí wákàtí àkókò ìrìn-àjò ju ohun tí a gbà ọ́ láàyè láti ṣe lọ.

21. **Kínni yóò ṣẹlẹ̀ tí mo bá ṣiṣẹ́ ju òdíwọ̀n àkókò ìrìn-àjò tàbí WWL mi lọ?**
    - Ìgbà kọ̀ọ̀kan tí o bá kọjá ìbèrè, a ó fún ọ ní àkíyèsí ìṣe àdéhùn tí a fọwọ́kọ àti àlàyé láti ọ̀dọ̀ DSHS tí ń rán ọ létí pàtàkì kí ó má ṣe àfikún-àkókò tí a kò fọwọ́sí. Àkíyèsí yìí ni a ó tún firánṣẹ́ sí (àwọn) oníbàárà tí o ṣiṣẹ́ fún àti àwọn aṣojú wọn.
    - Ní ìgbà kẹẹ̀ta ti ìbèrè àpọ̀jù, a le mú àdéhùn rẹ dópin tàbí ó le má lẹ́tọ̀ọ́ mọ́ láti gba ìsanwó fún ọjọ́ 90. Tí a bá mú àdéhùn rẹ dópin o gbọ́dọ̀ dúró fún ọjọ́ 90 kí o tó lẹ́tọ̀ọ́ láti ní àdéhùn titun míràn.
    - Tí o bá kọjá ọ̀sẹ̀ iṣẹ́ tàbí òdíwọ̀n àkókò irin-àjò rẹ púpọ̀ àti léraléra, DSHS le mú àdéhùn rẹ dópin fún àṣìṣe kí wọ́n sì kọ̀ láti fún ọ ní àdéhùn iṣẹ́ míràn.

22. **Fún ìgbà wo ni àwọn iṣe àdéhùn yóò fi wà lórí fáìlì àdèhùn mi?**

Ìṣe àdéhùn kọ̀ọ̀kan yóò wà níbẹ̀ fún oṣù 12 láti ọjọ́ àkíyèsí ìṣe àdéhùn náà. Lẹ́yìn oṣù 12, ìṣe àdéhùn náà dópin.

23. **Báwo ni mo ti le yàgò fún àwọn ìṣe àdéhùn?**
    - Máa ṣètò iṣẹ́ rẹ nígbà gbogbo ṣáàjú kí o sì máa kọọ́ sílẹ̀.
    - Tí àwọn àìní oníbàárà bá yípadà tí o sì ní láti ṣe iṣẹ́ ètò míràn tó nípa lórí WWL rẹ, kàn sí aṣàkóso ẹjọ́ oníbàárà náà lójú ẹsẹ̀.
    - Kọ àkókò iṣẹ́ rẹ sílẹ̀lórí ojú-ewé àkókò rẹ lẹ́yìn iṣẹ́ ọjọ́ kọ̀ọ̀kan tí o ṣiṣẹ́, o le ràn ọ́ lọ́wọ́ láti tún kọọ́ sílẹ̀ lórí kàlẹ́ndà. Máa ṣàyẹ̀wò nígbà gbogbo láti ṣàrídájú o wà láàrín WWL rẹ.
    - DSHS ní àwọn ohun ìrànwọ́ nílẹ̀ láti ràn ọ́ lọ́wọ́ àti agbanisiṣẹ́/oníbàárà rẹ kọ́ síwájú síi nípa ìṣàkóso ètò rẹ láti wà láàrín WWL rẹ. Àwọn ohun ìrànwọ́ wọ̀nyí wà nílẹ̀ ní www.dshs.wa.gov/altsa/IPOT.